26

# ÌHUN LÍTÍRÉṢỌ̀ KAN GẸ́GẸ́ BÍ ÀWÒRÁN ÀWÙJỌ AṢẸ̀DÁ LÍTÍRÉṢỌ̀ NÁÀ: ÀGBÉYẸ̀WÒ *ÌGBÌ AYÉ ŃYÍ* TÍ T.A.A. LÁDÉLÉ KỌ

Láti Ọwọ́

Adéyẹmí A. Adéyínká Ph. D.

University of Ìbàdàn

Department of Teacher Education

Ìbàdàn

Email: yemiadeyinka13@gmail.com

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

# Professor Philip Adedotun Ogundeji
## Festschrift Committee
*c/o Department of Linguistics and African Languages*
*University of Ibadan, Ibadan, Nigeria*

*Our Ref.* ____________

*Your Ref.* ____________ *Date:* ____________

---

**Dr Adeyemi A. Adeyinka** **21st September, 2016**
Department of Teacher Education
Faculty of Education
University of Ibadan

Sir,

**LETTER OF ACCEPTANCE**

We are pleased to inform you that your paper titled: ***Ìhun Lítíréṣọ̀ kan gẹ́gẹ́ bí Àwòrán Ìhun Àwùjọ Aṣẹ̀dá Lítíréṣọ̀ Náà*** has been accepted for publication in *New Trends in Yorùbá Language, Literature and Culture: A Festschrift in Honour of Professor Philip Adedotun Ogundeji (2016)*

The paper was subjected to a rigorous peer-review and it was found to be of good academic quality. The publication is in press and will be released soon.

Accept our congratulations.

Yours faithfully,

**Dr. C. A. Akangbe**
***Secretary***

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**Ìfáárà**

Lítíréṣọ̀ àti ẹ̀ka rẹ̀ ní í ṣe pẹ̀lú ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ ẹ̀dá nítorí ara àwùjọ ni àwon apohùn àti òǹkọ̀wé wà bẹ́ẹ̀ sì ni iṣẹ́ wọn dá lórí ohun tí ó ń lọ ní àyíká wọn. Fún ìdí èyí, iṣẹ́ yìí dá lórí àlàyé lórí àwọn kókó ọ̀rọ̀ inú pépà yìí, ohun tí lítíréṣọ̀ jẹ́, ohun tí à ń pè ní àwùjọ, ẹni tí à ń pè ní 'aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀' àti bí ìhun lítíréṣọ̀ kan ṣe le jẹ́ àwòrán ìhun àwùjọ aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ náà. Ìwé ***Ìgbì Ayé Ńyí*** (1978) tí Ládélé kọ ni a wò láti ṣe ìtúpalẹ̀ àlàyé wa.

Babalọlá (1967: 7) ni "'lítíréṣọ̀ ni àkójọpọ̀ ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè kan... ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ tí ó já sí ewì, àròfọ̀, ìtàn, àlọ́, ìyànjú, ìròyìn tàbí eré onítan, eré akọ́nilọ́gbọ́n lórí ìtàgé...''. Adéyínká (2012:67) ní tirẹ̀ pe lítíréṣọ̀ ní "ọ̀rọ̀ ẹnu Yorùbá tí ó kún fún ọgbọ́n, ìmọ̀, ìrírí, ìwà, ẹ̀sìn, ìṣẹ̀ṣe àti gbogbo ohun tí ó jẹ mọ́ ìwà àjùmọ̀ní láàrin wọn" nígbà tí Sànyà (2012:173) kín in lẹ́sẹ̀ pé "lítíréṣọ̀ kún fún ọ̀rọ̀ ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ó sì ń ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ àǹfààní fún àwùjọ tí a ti ń rí i". Ojú yòówù tí a lè fi wò ó, ó hàn gedegbe pé lítíréṣọ̀ jẹ́ àròjinlẹ̀ nípa ìwà, iṣẹ́, ọgbọ́n àti ìrírí àwọn ẹ̀dá. Ohun kejì tí a rí fà yọ nínú ọ̀kan-ọ̀-jọ̀kan ìtumọ̀ lítíréṣọ̀ ni pé ó lè wà ní àkọsílẹ̀ nítorí Ọ̀gínní (1982) pè é ní "àkọsílẹ̀ tí ó ń fi bí ayé ti rí hàn…" tàbí nínú ọpọlọ. Èyí tí ó fi hàn pé ìtumọ̀ tí ó fi lítíréṣọ̀ àwùjọ Yorùbá sọ́kàn wà nínú wọ́n. Ohun kẹta tí a rí nínú àwọn ìtumọ̀ yìí ni pé lítíréṣọ̀ kún fún iṣẹ́ ọnà èyí tí ó mú kí ó dùn ún kà kí ó sì dùn ún gbọ́.

Ẹ̀wẹ̀, nínú gbogbo oríkì tí a fún lítíréṣọ̀ yìí, kò sí èyí tí ó fi ẹnu ba orísìí ẹ̀ka tí a pín lítíréṣọ̀ Yorùbá sí ṣùgbọ́n Adébíyìí (2012:35) yànnàná èyí pé ẹ̀ka mẹ́ta pàtàkì ni a pín in sí - ìtàn àròsọ, eré onítàn àti ewì. Àlàyé ráńpẹ́ mìíràn tí a lè ṣe lórí lítíréṣọ̀ ni pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá pín sí oríṣiríṣi. Bí a ti rí àwọn káríayé bí ìjálá, ọfọ̀ , àyájọ́, ẹsẹ ifá, ẹ̀sà tàbí iwì, ìrèmọ̀jé, oríkì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, náà ni a rí ti àdúgbò bí olele ní ilẹ̀ Ìjẹ̀ṣà, alámọ̀ ní ilẹ̀ Èkìtì, ẹ̀fẹ̀ ní Ẹ̀gbádò, àsíkò ní Ìkálẹ̀ àti dadakúàdà ní Ìgbómìnà.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

**Àwùjọ**

Hornby (1974: 834) pe àwùjọ ní gbígbépọ̀ àwọn ènìyàn ní agbègbè kan, èyí tí ó túmọ̀ sí àgbájọ àwọn ènìyàn tí ìwà àti ìṣesí wọn bá ara wọn mu. Àwùjọ yìí náà ni Akìwọwọ (1983: 16) pè ní "aṣùwàdà". Bí a bá wo ohun tí àwọn onímọ̀ pè ní àwùjọ, a rí i pé ènìyàn ni ó ṣẹ̀dá àwùjọ àti pé àwùjọ yìí ni yóò tọ́ka sí lítíréṣọ̀ tí yóò wà níbẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Wellek àti Warren (1949) ṣe sọ pé "lítíréṣọ̀ ni ó ń sọ bí àwùjọ ṣe rí fún wa'' bẹ́ẹ̀ náà ni Adélékè (2005:172) tọ́ka rẹ̀ pé lítíréṣọ̀ ń ṣe àfihàn ìrírí ẹ̀dá ọmọ ènìyàn láti òkè délẹ̀ láìṣẹ́ nǹkankan kù. Kò sí àní-àní pé ènìyàn ni ó ń ṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ ní àwùjọ tí à ń wí yìí, èyí sì fi hàn wá pé àjọṣepọ̀ tí ó lóòrìn wà láàrin lítíréṣọ̀, ènìyàn àti àwùjọ.

Ta ni a lè pè ní aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀? Ẹnikẹ́ni tí ó bá ti lo èyíkéyìí nínú ẹ̀yà lítíréṣọ̀, yálà ewì, ìtàn àròsọ tàbí eré onítàn ni aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀. Lílò yìí wà lọ́wọ́ sísọ lẹ́nu nítorí pé òkú ni ohunkóhun tí a kọ sínú ìwé àfi ohun tí a sọ lẹ́nu nìkan ni ó jẹ́ ààyè. Kì í ṣe àwọn òǹkọ̀wé nìkan ni à ń pè ní aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ nítorí àwọn akéwì alohùn náà ń lo ohun èlò oríṣiríṣi bí ìlù, aṣọ àti ohùn èyí tí wọ́n fi ń fi ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ hàn.

Ohun mìíràn tí a lè ṣe àlàyé nípa àwùjọ ni pé àṣà, ọrọ̀-ajé àti ètò ìṣèlú ni ó gbé àwùjọ ró, àwọn wọ̀nyí ni a sì le lò láti mọ bi àwùjọ kan ṣe rí. Àwùjọ kọ̀ọ̀kan ni ó ní àṣà àti ìṣe rẹ̀ tí àwọn ènìyàn ń tẹ̀lé èyí tí ó sì ń mú ìrẹ́pọ̀ àti àlàáfíà wà nígbà tí kálukú bá ń ṣe e bí wọ́n ṣe ń ṣe é ṣùgbọ́n, ní kété tí ẹnìkan bá ti tàpá sí ohun tí ó jẹ́ àṣà àwùjọ, ìdàrúdàpọ̀ àti ìjà máa ń wáyé gẹ́gẹ́ bí Adélékè (2005: 171-185) ṣe ṣe àlàyé rẹ̀.

Ìrírí nípa ìhùwàsí àwùjọ ni ẹnìkọ̀ọ̀kan yóò fi mọ pé òfin de òun àti irú ìwà tí ó yẹ kí òun hù. Àwọn òfin wọ̀nyí ni ó wà nínú àṣà àwùjọ. Lára àṣà yìí ni a ti ní èèwọ̀, ẹ̀sìn, ètò ọrọ̀-ajé, ìtàn ìjìnlẹ̀ àti bí nǹkan ṣe jẹ́ sí ara wọn. Bákan náà, láti inú àṣà yìí ni ẹnìkọ̀ọ̀kan ní àwùjọ yóò ti kọ́ ìtàn àti lítíréṣọ̀ àwùjọ rẹ̀. Nítorí ìdí èyí ni a fi sọ pé lítíréṣọ̀ jẹ mọ́ àṣà àti èrò ìjìnlẹ̀ tí ó wà nínú àwùjọ kan. Ògúnṣínà (2010:9) wa ọkọ̀ èyí gúnlẹ̀ pé ìmọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò wà nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá, nípa bí ó ti ó fi hàn nínú eré-onítàn Bó Ti Gbà tí ó ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀.

Ẹ̀wẹ̀, ó yẹ kí á mọ̀ pé gbogbo àṣà, èèwọ̀, èdè àti èrò ọkàn yìí yàtọ̀ láti àwùjọ kan sí èkejì bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó gbà pé àmúwá Ọlọ́run ni ìyàtọ̀ yìí, pé ''àtẹ́wọ́ la bálà, a ò mẹni ó kọ wọ́n'' ni. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé "ọba ló nilẹ̀'' àtipé òun ni aláṣẹ èkejì òrìṣà, ọkọ le rẹ́ ìyàwó rẹ̀ jẹ; ọbá lè pa ó sì lè dá ẹ̀mí sí. Ohun tí ó ń ṣokùnfà ìgbàgbọ́ tàbí àṣà yìí ní ọ̀nà tí



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ẹnìkọ̀ọ̀kan ń gbà kó ọ̀rọ̀ jọ àti ìwọ̀nba àǹfààní ohun àmúṣògo tí a ní mọ. Williams (1978: 54) sọ nínú iṣẹ́ rẹ̀ pé:

> *It is not the consciousness of man that determines their being, but on the contrary it is their social being that determines their consciousness. (o.i 54)*
>
> *Kì í ṣe ìkíyèsí tàbí èrò ẹ̀dá ni ó lè ṣe okùnfà ìwàláyé rẹ̀, dípò èyí, ipò ẹ̀dá láwùjọ ni ó lè ṣe okùnfà ìkíyèsára rẹ̀. (o.i 54)*

Èyí ni pé ipò tí ènìyàn wà ló máa ń mú kí ènìyàn ronú bí ó ṣe rò ó. Lára àwọn nǹkan tí Williams gbà pé ó dá ìyapa sílẹ̀ láàrin àwọn ènìyàn ni ìpínsẹ̀, ọ̀nà tí a ń gbà rí oúnjẹ òòjọ́ àti ọ̀nà tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ń gbà kó ọ̀rọ̀ jọ. Tíọ̀rì tí ó ní ṣe pẹ̀lu àlàyé yìí ni ti Karl Marx èyí tí a ó fi ṣe ìtúpalẹ̀ ìwé ***Ìgbì Ayé Ń̄yí***.

**Tíọ̀rì Máàsì**

Karl Marx ni a mọ̀ sí agbátẹrù tíọ̀rì yìí. Ó fi ojú wo ìbẹ̀rẹ̀ ayé, tí ẹnìkankan kò dá ilẹ̀ tàbí ohun èlò kan ní fún ara rẹ̀. Nígbà tí ó yá, àwọn kan sọ ara wọn di alágbára nípa ogun, nípa lílo agbára, nípa owó tí wọ́n rí kó jọ tàbí nípa ipò tí a yàn wọ́n sí èyí sì ni ó fà á tí a fi rí àwọn kan tí wọ́n fi ara wọn sábẹ́ ààbò wọn fún ìrànlọ́wọ́. Àṣà yìí ni ó jẹ́ kí àwọn kan di ẹni àjí-tanná-wò, tí ó jẹ́ kí wọ́n dá ilẹ̀ ní tí àwọn kan sì di ẹni tí ó ń yá ilẹ̀ lò. Ní ọ̀nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ohun tí Marx ń sọ ni pé àwọn irinṣẹ́ ìpèsè kan wà tí ó jẹ́ dandan fún àwùjọ kọ̀ọ̀kan láti ní, àwọn wọ̀nyí sì ni ìpèsè oúnjẹ, ìpèsè ilégbèé àti ìpèsè ohun-èlò oúnjẹ àti ilégbèé. Tíọ̀rì yìí wòye pé ọ̀wọ́ àwọn ènìyàn kan ni ó ní àṣẹ lọ́wọ́ ní àwùjọ tí wọ́n sì fi ń jẹ gaba lórí àwọn ẹ̀dá tó kù. Ìjẹgàba nípa ọrọ̀ ajé àti ìṣèlú múmú láyà tíọ̀rì Marx èyí ni ó mú kí ó tako àṣa kí irinṣẹ́ ìpèsè wà ní ọwọ́ àwọn kan kí wọ́n sì máa lò ó láti jẹ gàba lórí àwọn mẹ̀kúnnù.

Síwájú sí i, Moyra (1999:100) ṣe àkíyèsí pé ọ̀gbun tí ó jìn ni ó ṣì wà láàrin àwọn olówó àti àwọn mẹ̀kúnnù ní àwùjọ wa nítorí pé àwọn tí ó ní náà ni ó ń sí i tí àwọn tálákà sì n pọ̀ sí i ní àwùjọ ní ojoojúmọ́. Adéríbigbé (2012:234) ní tirẹ̀, ṣàlàyé pé Marx àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ gbàgbọ́ pé bí àwùjọ kan yóò bá jẹ́ aláìlábàwọ́n, kò gbọdọ̀ sí ọ̀rọ̀ 'èmí jù ọ́, ìwọ́ jù mí níbẹ̀' nítorí náà, ìjà àti aáwọ̀ ọ̀wọ́ àwọn ènìyàn láwùjọ ni èrò Karl Marx dá lé lórí jùlọ. Tíọ̀rì yìí fẹ́ kí á máa lo ọ̀nà nípa èrò-báyéṣerí láti tú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ palẹ̀. Ó ń sọ pé ọ̀wọ́ àwọn ẹ̀dá kan ló ní àṣẹ lọ́wọ́ ní àwùjọ tí wọn



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

sì fi ń jẹ gàba lórí àwọn ọwọ́ ẹ̀dá tó kù. Ìyípadà àti ìfòpinsí ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni ó ń gún àwọn òǹkọ̀wé ní kẹ́sẹ́ láti fi iṣẹ́ wọn jà fún àwùjọ.

Kò sí àwùjọ kan tí ó wà lórí ilẹ̀ ayé lónìí tí kò ní ìlànà ètò ìṣèlú kan tí wọ́n yóò fi máa gbé ètò ọrọ̀-ajé, iṣèlú, àṣà àti ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ró. Ọ̀pọ̀ ènìyàn, pàápàá àwọn tí à ń ré jẹ lè má mọ̀ nípa irú ètò yìí. Tí òǹkọ̀wé kan bá wá dìde ní àwùjọ kan tí ó ń kọ̀wé lítíréṣọ̀, èrò tí àwùjọ rẹ̀ gbìn sí i nínú kò ní í ṣe aláìhàn nínú iṣẹ́ rẹ̀. Ìdí pàtàkì nìyí tí Barber (1979:11) fi ní:

> *Gbogbo lítíréṣọ̀ ni í fi àwọn ìrírí ayé, èrò àti ìgbàgbọ́ ọmọ ènìyàn hàn. Èyí kò sì ṣe aláìfi sí ibìkan.*

Òǹkọ̀wé lè kọ ìwé rẹ̀ láti fi gbe àṣà àwùjọ kan lẹ́sẹ̀ tàbí kí ó ta kò ó. Yálà òǹkọ̀wé kan gbé àṣà kan láruge tàbí ó ta kò ó, lára ìrírí tí ó ti ní àti èrò tí àwùjọ ti gbìn sí i lọ́kàn ni ó mú kí ó ṣe bẹ́ẹ̀. Láìsí àwùjọ, òǹkọ̀wé kò le kọ̀wé gbe àṣà kan tàbí kí ó ta kò ó. Gbogbo ìmọ̀ tàbí ìgbàgbọ́ tí ó wù kí òǹkọ̀wé kan ní, láti inú àwùjọ tí ó ti dàgbà ni ó ti wá.

**T. A. A. Ládélé àti *Ìgbì Ayé Ńyí***

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé alàgbà Ládélé ti re ìwàlẹ̀àsà ní àsìkò tí à ń ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀, iṣẹ́ yìí ṣì ń fọhùn lẹ́yìn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Yorùbá ṣe ń sọ pé 'bí onírèsé ò bá fíngbá mọ́, èyítí ó ti fín ò lè parun'. Iṣẹ́ ìwádìí Ọ̀pádọ̀tun (2003:106-107) jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé Theophilus Adéníyì Akíndélé ni àpèjá orúkọ òǹkọ̀wé yìí. A bí i ni ìlú Òkehò láàrin ọdún 1920 sí 1921. Ó lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ Ìṣià, Òkehò láàrin 1929 sí 1930 bẹ́ẹ̀ ni ó lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ni láàrin 1941 sí 1943, ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ni ti ìjọba ní 1951 àti ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ni onípò kejì ní 1954 sí 1955. Ládélé tún gba ìwé-ẹ̀ri Dípúlómà nínú ètò-ìkọ́ni ní Yunifásítì ti ìlú Ìbàdàn ní 1960.

Iṣẹ́ olùkọ́ni Ládélé yàn láàyò ó sì ṣe èyí ní oríṣìíríṣìí ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní Òkehò, Àgọ́-Àrẹ àti Ìṣẹ́yìn. Ní ilé-ẹ̀kọ́ girama Ọ̀ránỳan, Ọ̀yọ́, Ládélé kọ́ èdè Faransé láàrin 1964 sí 1973 bẹ́ẹ̀ ni ó ṣiṣẹ́ olùkọ́ni ní ilé-ẹ̀kọ́ olùkọ́ni Ìjẹ̀bú Divisional Teacher Training College ní 1960 sí 1961. Ládélé fẹ̀yìntì sí Anglican Modern School, Òyọ́ ní 1978. Olóògbé D.O. Fágúnwà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tí wọn kọ́ Ládélé ní èdè Yorubá, ọ̀nà-ìkọ́ni tí ó lò sì jẹ́ kí Ládélé nífẹ̀ẹ́ sí èdè náà. Onírúurú

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ìwé ni Ládélé ti kọ ṣùgbọ́n àkọ́já ewé rẹ̀ ni ***Jẹ́ N Lògbà Tèmi (1971)*** lẹ́yìn èyí ni ó gbé ***Ìgbà Ló Dé (1973)*** kí ***Ìgbì Ayé Ńyí*** tó tẹ̀lé e ní 1978.

Ìjà òmìnira ni ìwé yìí dá lé lórí, àwọn ìlú méjì tí ìjà yìí sì wà ní àárin wọn ni ìlú Ọ̀yọ́ tí ó jẹ́ Olú ìlú fún ẹkùn Ọ̀yọ́ ní ayé àtijọ́ àti Òkè-Ògùn tí ó jẹ́ àwọn ìlú tí ó wà ní kété tí a bá ti kọjá Odò Ògùn ní ọ̀nà Ìṣẹ́yìn. Abẹ́ Ọ̀yọ́ ni àwọn ìlú yìí wà tí Aláàfin sì ń lo àṣẹ bí ó ti wù ú lórí wọn. Ẹ̀wẹ̀, Ládélé jẹ́ ọmọ Òkehò, òkan lára ìlú Òkè-Ògùn ó sì gbé ìwé rẹ̀ ***Ìgbì Ayé Nyí*** *(1978)* ka ìjọba amúnisìn èyí tí ó dá lórí bí Ọ̀yọ́ ṣe di Òkè-Ògùn ní ìgbèkùn, ṣùgbọ́n ọ̀nà tí ó gbà ṣe èyí àti ìlò-èdè rẹ̀ yàtọ̀ sí ìwé mìíràn lórí ètò ìjọba amúnisìn ó sì fi ara sin ju ***Ọmọ Olókùn Ẹṣin*** ti Adébáyọ̀ Fálétí kọ lọ. Olú Òtólú ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí Aláàfin tí àwọn ará ìlú sì dúró gẹ́gẹ́ bí ará Òkè-Ògùn. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ nínú ìjà òmìnira inú ***Ìgbì Ayé Ńyí*** ni pé ará Òkè-Ògùn (Bánkárere àti Bàkó) ni ó bẹ̀rẹ̀ ìjà òmìnira ṣùgbọ́n àwọn Gẹ̀ẹ́sì ni ó fún wọn ní òmìnira náà.

Nínú **Ọmọ Olókùn Ẹṣin**, a rí i pé àwọn ará Òkè-Ògùn ni ó gba òmìnira fúnra wọn ṣùgbọ́n nínú ***Ìgbì Ayé Ńyí***, àwọn Gẹ̀ẹ́sì ni ó rò pé ìjẹgàba àwọn olówó àti ọlọ́rọ̀ ìlú ti tó, tí wọ́n sì gba òmìnira fún àwọn Òkè-Ògùn, ìjọba kúrò ní ìjẹgaba ó sì di ti àparò-kan-ò-ga-ju-ọ̀kan-lọ. Ayé ọba lọ, ti mẹ̀kúnnù ló kù.

*Omi o, omi o, a ò mà mà r'omi mọ́ o*

*Omí lọ l'aye, pẹ̀tẹ̀pẹ́tẹ̀ l'ó kù*

*Ọba o, ọba o, a ò mà mà r'ọba mọ́ o*

*Ọba lọ l'aye, àwòrán l'ọbá dà.(o.i.60)*

Iyì, ọlá àti ẹ̀yẹ tí àwọn Yorùbá ń fún ọba àti ọmọ wọn ní ayé ìgbàkan ti dínkù. Bí ọbá tilẹ̀ ń kọjá ní òde-òní, ẹni tí ó bá wù ni yóò kí i (láìsí ohun tí ọba yóò ṣe). Ìwọ̀nba sì ni ohun tí ọba ìlú le ṣe lórí ọmọ ìlú ní òde-òní nítorí pé ayé ti di ayé òyìnbó, ó ti di ayé òfin. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì lu òfin ní òde-òní, dandan ni kí ìjìyà tí ó tọ́ wà fún un. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, a ti rí ìlú tí ilé-ẹjọ́ ti rọ ọba ní oyè rí bẹ́ẹ̀ ni a ti gbọ́ bí ilé-ẹjọ́ ṣe pàṣẹ kí ọba tí ó wà lórí ìtẹ́ kúrò lórí rẹ̀ fún ẹlòmíràn nítorí pé ọ̀nà tí ó gbà dé ibẹ̀ kò bá òfin mu.

Bí a bá fi ojú tí àwọn afojú-èrò-Marx-wo-nǹkan fi wo ìwé ìtàn àròsọ ***Ìgbì Ayé Ńyí*** tí Ládélé kọ, a ó ri pé bí ó ti wà ní lìkì náà ni ó wà ní gbangba. Bí irinṣẹ́ ìpèsè ṣe yàtọ̀ ní Améríkà,

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ni ó yàtọ̀ ní Rọ́ṣíà, ní ilẹ̀ Yorùbá àti ní àwùjọ kọ̀ọ̀kan. Bí ènìyàn bá ka ìwé ***Ìgbi Ayé Ń́yí,*** yóò ri pé ó ní irú èrò tí àwùjọ Yorùbá máa ń gbìn sí àwọn ọmọ lọ́kàn. Irú èrò yìí a máa jẹ mọ́ àṣà, èèwọ̀, èdè, òfin, ẹ̀sìn, ètò òṣèlú àti ọrọ̀-ajé ti ilẹ̀ Yorùbá. Ìdílé tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ti jáde wá tún lè hàn nínú ìṣesí ènìyàn. Lára irú èrò tí àwùjọ ti gbìn síni lọ́kàn ni kí ìdílé kan máa jẹ oyè kan ní àjẹwọ̀ kí àwùjọ sì gbà bẹ́ẹ̀ pé "olówó ni ẹ fún ní ọ̀rọ̀ sọ, ọ̀rọ̀ ò dùn lẹ́nu táláká''. Ìdí yìí ni ó mú kí ọba Abíọ́dún Adégoólú nínú ***Baṣọ̀run Gáà** ṣe* fẹ́ fi ọmọ rẹ̀ rọ́pò ara rẹ̀ bí ó bá wàjà.

Nínú ***Ìgbì Ayé Ń́yí,*** ó dájú ṣáká pé ètò òṣèlú tí ó jẹ mọ́ ti olówó-ló-layé ni èyí tí a rí fàyọ nínú rẹ̀. Nínú irú ètò yìí ni ọba jíjẹ máa ń wà, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹnìkọ̀ọ̀kan máa ń sáré láti kó ọrọ̀ jọ. Ní irú àwùjọ yìí, ogun abẹ́lé máa ń wà ní ààrin àwọn tí kò ní èlò àmúṣẹ̀dá nítorí pé wọn yóò maa tiraka láti kúrò nínú ìṣẹ́ kí àwọn náà sì kó ọrọ̀ jọ.

Nínú ìwé yìí a rí i pé Ládélé ṣe àfihàn àṣà kí ọbá jẹ ayé lórí àwọn ènìyàn kí ó sì máa jẹ ayé 'kò-séni-tí-yóò-mú-mi' kí àwọn ọmọ wọn sì máa lu ìlù "bámúbámú la yó, àwa ò mọ̀ pébi ń pa ọmọ ẹnìkankan''. Àmọ́ Ládélé kò fi ara mọ́ àṣà kí ọba jíjẹ parẹ́ bí kò ṣe kí á dín àṣẹ àti agbára wọn kù. Bákan náà ni kò fẹ́ kí ìyà ó jẹ àwọn mẹ̀kúnnù gbé. Nínú ìwé yìí kan náà, a rí i pé Ládélé kò sọ pé nítorí pé àwọn kan jẹ́ mẹ̀kúnnù, kí wọ́n máa ṣe ohun tó wù wọ́n, ó gbàgbọ́ nínú kí ìjìyà tí ó tọ́ wà fún ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣi ìwà hù ní àwùjọ. Púpọ̀ nínú ìwé tí Ládélé kọ ni ó dá lórí ìgbà àti àṣà àtijọ́ ṣáájú wíwá àwọn Gẹ̀ẹ́sì sí ilẹ̀ Yorùbá àti ìtàn bí àwọn òyìnbó ṣe dé sí ààrin wa tí wọ́n sì mú àṣà, ẹ̀sìn àti ọrọ̀-ajé wọn tọ̀ ìran Yorùbá wá. Èyí hàn nínú àwọn ìwé rẹ̀ bí ***Jẹ́ Ng Lo Gba Temi*** *(1971),* ***Ìgbà Ló Dé*** (1973) àti ***Ìgbì Ayé Ń́yí*** *(1978).*

Ohun kan tí ó yẹ kí á tọ́ka sí ni pé Ládélé ní àǹfààní láti gbé ní ìlú Ọ̀yọ́ tí ó jẹ́ olórí ìlú tàbí ìlú amọ̀nà ní ẹkùn Ọ̀yọ́ ní ayé àtijọ́, ó sì ní àǹfààní láti mọ gbogbo ohun tí ojú àwọn ará Òkè-Ògùn ń rí lábẹ́ Ọ̀yọ́ gẹ́gẹ́ bí Adébáyọ̀ Fálétí tí ó jẹ́ ọmọ Ọ̀yọ́ náà ti kọ ọ́ nínú ***Ọmọ Olókùn Ẹṣin*** *(1969).* A ó máa ṣe àlàyé nípa èyí níwájú.

**Àìdọ́gba Àwùjọ**



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Nínú ***Ìgbì Ayé Ń̀yí,*** ohun tí a lè sọ pé ó dálé lórí ni àìdọ́gba tí ó wà ní àwùjọ, a rí ibi tí irinṣẹ́ tàbí èlò àmúṣẹ̀dá ti rọ̀ sí ọ̀dọ̀ àwọn díẹ̀ tí wọ́n sì ń lo èlò yìí bí ó ṣe wù wọ́n tí àwọn ará ìlú sì gbà pé ''àtẹ́wọ́ la bálà, a ò mẹni ó kọ ọ́'' ni àti pé ''kí á ṣe é bí wọ́n ṣe ń ṣe é...'' Wọ́n ka ọba Òtólú sí ẹni tí ó ní agbára ààyè àti ikú tí ẹnikẹ́ni kò sì gbọdọ̀ ta ko agbára rẹ̀. Ládélé tilẹ̀ sọ nínú ìwé yìí pé:

> *Àwọn Yorùbá ní ọ̀wọ̀ tó kọyọyọ láti bù fún ọba wọn. Àní ìgbàgbọ́ wọn ni pé Ọlọ́run láyé yìí ni ọbá jẹ́, fún ìlú... ọ̀wọ̀ yìí àti ìgbàgbọ́ yìí win àwọn ọba mìíràn sí dé ibi pé ìlò ẹran-ọ̀sìn ni wọ́n ń lo àwọn ìpẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìlú. (o.i. 3)*

Agbára àwọn ọba àti ayé alárátá tí àwọn ọmọ wọn ń jẹ ni a rí tí ọba Tẹ́ní-ọlá tí a fi jẹ Olú Òtólú ń jẹ ayé àjẹyírakábá tí ó ń gba ẹrù ẹlẹ́rù, pàápàá jùlọ àwọn ọmọ ìlú Òtólú àti ti ìlú àmọ́nà kún tirẹ̀, "àrà tí ó bá wu ògódó ni ó lè fi imú olówó rẹ̀ dá, ibi tí ó wu ẹlẹ́nu ni ó le rán ẹnu rẹ̀ lọ'' ni ọ̀rọ̀ ọba àti àwọn mẹ̀kùnnù ni àsìkò yìí:

> *Ọba ló lowó ọba ló loko...ọba ló ni ọ́ tiwọ ti dúkìá rẹ. Bó bá wu ọba, ó lè ránṣẹ́ sí ìlú tó bá wù ú, a ní kí wọ́n fi igba géńdé ránṣẹ́ sí òun, kí wọ́n wá roko fún òun; bó bá wù ú, a ní kí wọ́n mú àwọn wúńdíá rọ̀gbọdọ̀rọgbọdọ tó jojú ní gbèsè bí mẹ́rin mẹ́rin wá láti ìlú kọ̀ọ̀kan, kí òún sà, kí òún rọ̀, kí òún fi àwọn tó bá wu òun ṣaya fúnra òun tàbí fún ọmọ òun... (o.i. 6)*

Ìwà 'ta ni yóò mú mi' yìí win àwọn ọba sí tóbẹ̀ẹ̀ tí ó fi jẹ́ wí pé kò sí ohun tí Tẹ́ní-ọlá lè dá ṣe ní ààfin- wọ́n ń nù ún ní oúnjẹ, wọ́n ń wẹ̀ fún un, wọ́n ń bá a tọ̀ àti yàgbẹ́ ni parípari rẹ̀ ni pé ẹnìkan wà ní ààfin tí wọ́n ń pè ní Ajìtó-ọba, ẹni tí ó jẹ́ pé ẹnu rẹ̀ ni ọba máa ń tu itọ́ tí ó sì máa ń ha kẹ̀lẹ̀bẹ̀ sí tí òun náà yóò sì fi tayọ̀-tayọ̀ gbé e mì. Orísirísi nǹkan mìíràn ni àwọn mẹ̀kúnnù ń ṣe fún ọba- ọ̀tọ̀ ni Anuba wà, ọ̀tọ̀ sì ni iṣẹ́ Tọbaṣẹ ní ààfin. Kékeré wá ni ti ọba lára kísà tí àwọn ọmọ rẹ̀ ń ṣe fún àwọn ará ìlú àti ìlú àmọ́nà. Àwọn ọmọ ọba wọ̀nyí máa ń rin "ìrìn ilé ọlá kiri''. Ìrìnàjò yìí sì le gba oṣù kí wọ́n tó padà sílé. Ní àsìkò ìrìnàjò wọn, ẹrù àti owó tí wọ́n ń kó bọ̀ máa ń pọ̀ tóbẹ̀ẹ̀ tí ó jẹ́ wí pé ó lè tó ọgọ́rùn-ún géńdé tí yóò ru ẹrù yìí dé Òtólú. Èyí tí wọ́n bẹ̀rù jù nínú àwọn ọmọ ọba yìí ni Adéríbígbé tí wọ́n ń kì ní:



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

*Adéríbigbé ọmọ Ajímájàsán*
*Ọ̀jobìjobì jẹran gbígbẹ*
*Ẹnìkan kì í pagún*
*Ẹnìkan kì í figún bọrí*
*Ara wọn ni wọ́n ń ṣe. (o.i. 7)*

Àyè gba Déégbé ní ìlú tóbẹ́ẹ̀ tí ó fi ń bẹ́ ènìyàn tí ó sì jẹ́ pé àjẹgbémì ni ti kàlòkàlò ni ọ̀rọ̀ rẹ̀ "igi tí Ṣàngó bá pa àpagbé'' ni, kódà, òun gan-an ni à bá máa pè ní ''Alápadúpẹ́'' nítorí pé ẹ̀bẹ̀ ni àwọn ará ìlú tún máa ń bẹ̀ ẹ́ tí wọ́n sì ń dúpẹ́ ní ọwọ́ rẹ̀ fún ohunkóhun tí ó bá ṣe.

Ìwá Déégbé yìí kò yàtọ̀ sí ti Òbé àti Ọláyìíòtán nínú ***Baṣọ̀run Gáà***. Gẹ́gẹ́ bí Adéríbigbé ti ṣe gun àwọn àgbẹ̀ tí ó ń ti oko wọn tí ó wà ní etí Sàárẹ́ lọ sí Làágbé náà ni Òbé gun Akínkúnmi lẹ́ṣin nígbà tí wọ́n ń ti ilé àna Ọláyìíòtán bọ̀. Gáà fúnra rẹ̀ fi ìdí ọ̀rọ̀ yìí múlẹ̀ nígbà tí ó ń bá àwọn ọmọ, ìjòyè àti Gbági, ẹrú rẹ̀ sọ̀rọ̀ lẹ́yìn tí ọba Adégoólú ti lọ yíkàá fún un ní ilé rẹ̀:

*Àt'Òbé, àt'eyi Ọláyìíòtán*
*Àti Gbagi t'o npe'ra rẹ̀ l'agba ẹrú wa*
*Gbogbo nyin ẹ maa sọ ṣe*
*Òkìkí nkan n'ikan àbùkù*
*Ìyìn mba mi bi o ti wu mi*
*Pe aiye alarata ni gbogbo nyin njẹ... (o.i 52)*

Gbogbo ìwà burúkú àti ọ̀nà èrú tí Tẹ́ní-ọlá àti àwọn ọmọ rẹ̀ ń gbà kó ọrọ̀ jọ yìí kò tó wọn, ohun tí Tẹ́ní-ọlá tún ṣe ni pé kí ó máa fi òru bojú láti láti kó ilé tí kò sì sí ẹni tí ó rí i mú; àwọn tí ó sì mọ̀ pé ọba ni kò le sọ nǹkankan títí ìgbà tí Bánkárere fi tu àṣírí.

Bí àwọn ọba ti ní àṣẹ lórí ìlú wọn tó tí àwọn ará ìlú ò sì ní àǹfàání láti fi ẹ̀hónú wọn hàn, síbẹ̀ a rí àwọn kọ̀wọ̀sí kọ̀ọ̀kan tí kò kọ̀ kí ọ̀sán dòru nítorí àti gba ara wọn tàbí ènìyàn wọn sílẹ̀ nínú ìgbèkùn. Ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan ni irú àwọn ènìyàn yìí máa ń wà ní àwùjọ, a sì lè sọ pé ti wọ́n jẹ́ àrà ọ̀tọ̀ yálà nítorí ìrírí tí wọ́n ní nínú àwùjọ mìíràn bí i Bàkó tí ó ti gbé ìlú Èkó fún ọdún pípẹ́ kí ó tó padà sí Òtólú tàbí kí ó jẹ́ pé Olódùmarè ni ó fi iṣẹ́ yìí rán wọn gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí Àjàyí nínú ***Ọmọ Olókùn Ẹṣin***, Láwúwo nínú ***Rẹ́rẹ́ Rún***, Lísàbi nínú ***Lísàbi Agbòǹgbò Àkàlà***, àti Bánkárere nínú ***Ìgbì Ayé Ńyí***.

Ẹ̀wẹ̀, ìjà òmìnira tí àwọn kan máa ń ṣe agbátẹrù rẹ̀ yìí máa ń kó wọn sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyọnu àti àìbalẹ̀ ọkàn. Ó máa ń kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyà jẹ wọ́n tóbẹ́ẹ̀ tí ó fi jẹ́ pé 'ẹni tí ó bá fi orí tì í títí dé òpin ni

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

a ó gbàlà' ni ọ̀rọ̀ náà. Ní ìgbà míràn ẹ̀wẹ̀, ìjà òmìnira máa ń la ikú lọ, èyí tí ó jẹ́ wí pé àwọn àtẹ̀lé aṣíwájú yìí níláti tẹ̀ síwájú.

Nínú ***Igbi Aye Nyi***, Bánkárere àti Bàkó ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ẹgbẹ́ ajìjàgbara nítorí àwọn ni wọ́n tako ìwà Olú Òtólú tí ó sì mú kí ìrọ̀rùn dé bá àwọn mẹ̀kúnnù. Bánkárere ni a kà sí ẹni tí ó kúndùn ọ̀rọ̀ sísọ, kò sí ẹni tí kò le sọ ọ̀rọ̀ sí ní àwùjọ. Gẹ́gẹ́ bí Ládélé ṣe sọ:

> *Kò sí ẹni tí Bánkárere kò le gba àgbékà ọ̀rọ̀ fún, láìṣe àgbékà pẹ̀tẹ̀ẹ̀sì. Ó lè bú igi tútù kó d'ẹ̀gbẹ. Ó lè bú ènìyàn kí ó bínú lọ pokùnso. Ó lè bú eégún k'ó ṣí'ṣọ lórí. (o.i.47 )*

Ọ̀rọ̀ sísọ láìbikítà ni ó mú kí Bánkárere fi ìbínú sọ̀rọ̀ sí ọmọ ọba nílé ẹmu ní ọjọ́ kan tí ó sì ṣí aṣọ lójú eégún pé olè ni kábíyèsí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ti fà á létí wí pé kí ó má sọ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ní àwùjọ. Bánkárere ni:

> *Hẹ̀ẹ̀, Akàn aruga. Bí wọn yó ti máa ṣe fáàrí ọ̀fọ lọsan ni yẹn; bí ó bá di òru ni wọn yó máa dápọ̀ mọ́ àgùtàn kiri. Kúkúrú lọsan, gbọ̀ọ̀rọ̀ lóru, ènìyàn lọsan olè lóru. (o.i. 33)*

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "kí odi ó le gbọ́rọ̀ ni a ṣe ń sọ ọ́ lójú ọmọ rẹ̀'' ọ̀rọ̀ tí Bánkárere sọ yìí fi ìyà jẹ é púpọ̀ èyí sì yàtọ̀ pátápátá sí ohun tí ó máa ń wí nígbà tí wọ́n bá kìlọ̀ fún un nípa ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀, á ní:

> *Ẹ kò ará yín dà sóhun, ọjàre. Ọ̀rọ̀ tí mo sọ yi kò le ya mi lẹ́nu, àfi bí yó ba ya mi l'áṣọ l'o ku. (o.i. 4)*

Ohun tí a lè tọ́ka sí nípa Bánkárere ni pé ọ̀rọ̀ ni ó jẹ́ idà ogun tí ó lò láti ja ìjà òmìnira bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ó na pápá bora lẹ́yìn tí ó ti sọ ọ́ nítorí kò ní aláfẹ̀yìntì. Aáyan tí Bánkárere ń ṣe láti gba àwọn mẹ̀kúnnù lọ́wọ́ àwọn alágbára ni a rí i pé inú àwọn ènìyàn ò dùn sí nítorí pé wọ́n fi ìmọ̀ ṣe ọ̀kan pé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ tú àṣírí ọba nígbà tí Bánkárere sì tú àṣírí yìí, gbogbo àwọn ara ile rẹ̀ sálọ ní ìlú dípò kí wọ́n kín Bánkárere lẹ́yìn. Kódà pẹ̀lú àre tí àwọn oníyàwó Àdántán jẹ lórí pé Adéríbigbé àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ lọ fìnràn, wọ́n s ì fi ìyà jẹ wọ́n, oṣù mẹ́ta ni baálẹ̀ Àdántán lò ní Òtólú tí ó fi ń ra ọwọ́ ẹ̀bẹ̀ sí Olú, inú ìrònú yìí ni ó sì kú sí. Lẹ́yìn oṣù mẹ́fà àwọn ará Àdántán ní Òtólú ní Tẹ́ní-ọlá tó dá wọn sílẹ̀ pẹ̀lú inawó-nára wọn.

Bàkó ní tirẹ̀ jẹ́ ọmọ Òtólú tí ó ti lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ní ìlú Èkó kí ó tó padà wá sí ilé. Bámimọ́rẹ́ gan-an ni orúkọ rẹ̀ ń jẹ́, ìgbà tí ó dé Èkó ni ó pa orúkọ dà sí Bàkó-ń-mọ́kà ó sì di ọ̀kan nínú àwọn tí ó ń ṣánko àgbàlá Gómìnà ní Èkó. Bàkó ti ní àǹfààní láti mọ bí ìjọba àparò-kan-ò-ga-



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ju ìkan lọ ṣe rí àti bí àjọgbé ṣe jẹ́ ní Èkó, ó sì ka ara rẹ̀ sí ọ̀làjú tí ó nílàti fi ọ̀nà han àwọn mìíràn nígbà tí ó padà sí Òtólú.

Ohun èlò tí Bàkó lò nínú ***Ìgbì Ayé Nyí*** ni ìrírí àti ọ̀rọ̀ ẹnu. Ládélé sọ pé Bàkó a máa mu ẹmu, ó sì le sọ̀rọ̀, àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni ó máa ń kó àwọn ènìyàn jọ tí yóò sì máa sọ oríṣiríṣi ìtàn nípa Èkó fún wọn. Bàkó kò bẹ̀rù ẹnìkan, ìdí sì nìyí tí ìjà fi wáyé láàrin rẹ̀ àti Déegbé ọmọ ọba. Déegbé ni ó tún gbé ìṣe rẹ̀ wọ ìlú, bí àwọn ènìyàn bá sì ti gbúròó rẹ̀, kálukú máa ń pa ara mọ́ ni ṣùgbọ́n Bàkó kò ṣe èyí, Déegbé sì gbá etí rẹ̀. Bàkó kò bẹ̀ṣù-bẹ̀gbà, ó kó ẹ̀ṣẹ́ bo Déegbé, èyí sì mú kí Déegbé gé etí ọ̀tún Bàkó. Àṣẹ̀yìnwá àṣẹ̀yìnbọ̀ ọ̀rọ̀ yìí, Bàkó lọ fi ẹjọ́ sùn ní Èkó, èyí sì di ohun tí Olú Òtólú ń lo ọdún kan tí Déégbè sì lo ọdún mẹ́ta ní ẹ̀wọ̀n sí.

Lẹ́yìn tí Tẹ́ní-ọlá àti ọmọ rẹ̀ ti wọ ẹ̀wọ̀n, wọ́n fi Lábándé jẹ oyè Olú Òtólú ṣùgbọ́n ohun tí a rí ni pé àṣà ọba ló nilẹ̀ ti gbilẹ̀ púpọ̀ ní àwùjọ tóbẹ́ẹ̀ tí ọba àti ọmọ rẹ̀ Olátóngẹ́ẹ́ tún bẹ̀rẹ̀ sí ni àwọn ará ìlú lára. Kódà àgọ́ ọlọ́pàá àti àwọn ohun mìíràn tí ìjọba ṣe sí ìlú kò dín agbára ọba kù láàrin àwọn ará ìlú. Tóngẹ́ẹ́ ń jẹ ayé bí i Déégbè ṣùgbọ́n ó gùn ẹṣin abómú nígbà tí ó yá. Ìtàn ohun tí ó gbé Tẹ́níọlá, ọba àná, dé ọgbà ẹ̀wọ̀n ní Èkó tí kò sì lè padà sí ìlú mọ àti bí ìjọba ṣe kọ́ àgọ́ ọlọ́pàa sí Òtólú láti máa pèsè àlàáfíà ìlú mú kí baálẹ̀ fi ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n ṣe ọgbọ́n, ó rántí ohun tí ó kọjá ó sì fi ọgbọ́n gba ọmọ àti ara rẹ̀ sílẹ̀.

**Ipa Ètò Ìṣèlú Àwa-Arawa**

Nínú ìlú yìí kan náà, a rí pé ìyípadà ti dé nítorí àwọn ọmọ ìlú tí ó wà ní ìlú Èkó tí ń darí sílé dìẹ̀dìẹ̀. Lára àwọn wọ̀nyí ni Bánkárere àti Bàkó tí wọ́n dá ẹgbẹ́ Àbọ̀dé sílẹ̀, wọ́n ń sowọ́ papọ̀, wọ́n sì ń tún ìlú ṣe. Bánkárere ni Alága ẹgbẹ́ tí Bàkó sì jẹ́ Akọ̀wé. Àwọn ará ìlú fẹ́ràn ẹgbẹ́ yìí nítorí ọjà oríṣiríṣi tí wọ́n ń kó wọ ìlú tí owó wọn kò sì wọ́n àti nítorí owó tí wọ́n ń yá àwọn tí ó bá wà nínú ìṣòro.

Gbogbo bí ẹgbẹ́ Àbọ̀dé ti ń ṣe tí inú àwọn ará ìlú ń dùn ni inú Olú Òtólú, Lábándé, ń bàjẹ́ páápàá nítorí àìsọ fún un kí ẹgbẹ́ yìí tó kó ara wọn jáde. Olú Òtólú rò ní ọkàn ara rẹ̀ pé kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ imú ẹlẹ́dẹ̀ ẹgbẹ́ Àbọ̀dé tí wọ́n yí sí Amúlùúdùn ń wọ ọgbà àti pé èyí lè jẹ́ ọ̀nà láti gbógun ti ìjọba òun. Ohun tí ó ṣe láti mú òpin bá ètò ẹgbẹ́ yìí ní ọjọ́ tí wọ́n ń ṣe àjọ̀dún kẹta ẹgbẹ́ wọn ní ọjà ni pé:



UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

*Ó pe Ṣẹ́tẹ̀-ọ̀tá ti Rẹ́hìn-odì..., o ni ti wọn ba ti d'oju-agbo àwọn Ẹgbẹ Àbọ̀dé, ìgbájú-ìgbámú ni ki wọn fi ṣe ti awọn onílù ati aluṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ ibẹ. (o.i.73)*

Ṣé "ẹni tí ó rán ni níṣẹ́ ni à ń bẹ̀rù, a kì í bẹ̀rù ẹni tí a ó jẹ fún'', àwọn ìránṣẹ́ ọba Lábándé ṣe gẹ́gẹ́ bí ọba ṣe rán wọn, wọ́n pa itú méje tí ọdẹ ń pa nínú igbó, ìjà ọjọ́ náà kò ṣe é ròyìn; agbára àwọn ọlọ́pàá kò ká a, àfi ìgbà tó rẹ̀jà gẹ́gẹ́ bí Ládélé ti ṣàlàyé. Nínú ìjà yìí ni Ṣẹ́tẹ̀-ọ̀tá àti Rẹ́hìn-odì kú sí tí ọ̀rọ̀ sì di ohun tí Gómìnà ti ìlú Èkó wá sí.

Ìrìnàjò Gómìnà sí Òtólú fi agbára àwọn ọba àti àṣà 'àtẹ́wọ́ la bálà, a ò mẹni tó kọ ọ́' àti pé 'kí á ṣe é bí wọ́n ti ń ṣe é kí ó le rí bí ó ti ń rí' hàn. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwádìí àti ifọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò tí àwọn ọlọ́pàá ṣe, Gómìnà ṣe ètò bí agbára yóó ṣe kúrò ní ọwọ́ ọba tí yóò wà ní ọwọ́ ará ìlú tí ọba yóò sì jẹ́ olùdámọ̀ràn lásán. Gómìnà pín Òtólú àti àwọn ìlú àmọ́nà sí mẹ́ta èyí tí a lè fi wé ìjọba ìbílẹ̀. Nígbà tí Òtólú jẹ́ olú-ìlú fún ìjọba ìbílẹ̀ kan tí àwọn ìlú méjì yòókù náà sì ní olú-ìlú wọn àti olórí, Olú Òtólú ni ó jẹ́ olórí fún gbogbo ìlú tàbí ìjọba ìbílẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. A lè sọ pé Olú Òtólú ni ó jẹ́ Alága ìgbìmọ̀. Ohun mìíràn tí Gómìnà ṣe ni pé dípò tí Olú Òtólú nìkan yó fi máa pàṣẹ gẹ́gẹ́ bí olórí, yóò ní àwọn díẹ̀ tí wọ́n jẹ́ ọmọ ìlú... gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ràn. (o.i. 85). Bàkó ni ó jẹ́ alága fún ìbílẹ̀ Òtólú tí Bánkárere àti Majeti-ọba-o-di jẹ́ ọmọ ìgbìmọ̀. Gómìnà tún fi kún un pé Olú Òtólú kò gbọdọ̀ rí àṣàdànù nínú ìmọ̀ràn yìí.

Àṣà tuntun tí ó tún dé ni pé ìjọba yóò máa fún ọba àti ìjòyè ní owó oṣù, kí ìwà ìlọ́nilọ́wọ́gbà àti ìrẹ́jẹ le kúrò ní Òtólú. Gómìnà tún pàṣẹ pé kí gbogbo súnmọ́ba gba ile wọn lọ kí wọ́n sì lọ wá iṣẹ́ ṣe. Nígbà tí Lábándé gbọ́ gbogbo ìyípadà yìí tí ó sì ro àròjinlẹ̀ ní orí rẹ̀, àgbálọ-gbábọ̀ ọ̀rọ̀ rẹ̀ ni pé

*... ó dára. Ibi tí ìgbì ayé yí mi sí yìí náà dára. (o.i 90)*

Ṣé Yorùbá bọ́, wọ́n ní 'bí ènìyàn ò bá gba kádàrá, yóò gba kodoro', Olú Òtólú gbà nítòótọ́ pé aṣọ ìgbà ni ó yẹ kí á lò fún ìgbà àti pé ìgbà ló dé, ibi tí ayé bá ń yí sí ni ó yẹ kí á yí sí.

*Ìgbì ayé ń yí lóòótọ́. Ejò wa wọ́ kúrò níbi t'àná.*
*Ayé kúrò lọ́wọ́ ọlá, ó bọ́ s'ọ́wọ́ tálákà... (o.i 92)*

Níwọ̀n ìgba tí ó jẹ́ pé lára àwùjọ ni òǹkọ̀wé wá, inú àwùjọ ni ó ti ní ìrírí tí ó ń lò, gbogbo èrò tí ó ní lọ́kàn tí ó sì ń mú lò, àwùjọ ni a gbà pé ó gbin irú èrò bẹ́ẹ̀ sí i lọ́kàn. Ìdí nìyí tí kò fi ṣe é

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

ṣe fún òǹkọ̀wé láti ta kété sí iṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ rẹ̀. Èyí ni ó fà á tí ìwé tàbí ìtàn àròsọ kan fi ní láti bá ìgbà kan mu.

Nígbà tí a bá ń yẹ ìwé ìtàn àròsọ kan wò, ó yẹ kí á wo ohun tí iṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn náà dá lé lórí nítorí ó ṣòro láti ya lítíréṣọ̀ kúrò lára àṣà àti iṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Iṣẹ́ tí òǹkọ̀wé ń ṣe, gẹ́gẹ́ bí Eagleton (1976) ti sọ, ni pé iṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni òǹkọ̀wé ń fi ẹnà sọ. Ó ní:

> *The writer translates social facts into literary ones, and the critic's task is to de-code them back into reality.*
>
> *Ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ pàtó ni òǹkọ̀wé máa ń gbé wò nínú iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ tí àwọn láméyítọ́ yóò sì túmọ̀ iṣẹ́ ọnà wọ̀nyí sí iṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé.*

A le ṣe àlàyé pé ètò ìṣèlú ní ilẹ̀ Yorùbá ṣáájú wíwá àti ìjẹgàba àwọn Gẹ̀ẹ́sì ni ìwé ìtàn àròsọ ***Ìgbì Ayé Nyí*** dá lé lórí. Àṣà tí ó súyọ nínú ìwé náà ni ìjọba ìjẹgàba níbi tí a ti ka àwọn ọba sí 'aláṣẹ èkejì òrìṣà'. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí ọba Òkò nínú ***Ọmọ Olókùn Ẹṣin*** tí ó ń ṣe àkóso àwọn ìlú Òkè-Ògùn náà ni a rí Olú Òtólú tí ó jẹ́ alákòóso lórí ìlú rẹ̀ àti ìlú àmọ̀nà tí ó lé ní igba. Ọba yìí ni ó ń mú àwọn ará ìlú sìn, ohun tí ó bá sì wù ni ó le fi wọ́n ṣe.

Nítòótọ́, àṣà kí ọba máa pàṣẹ ti wà kí àwọn òyìnbó tó dé, síbẹ̀ a rí i pé ipò àwọn ọba ní ilẹ̀ Yorùba àti àwọn yòókù wọn ní ilẹ̀ Haúsá àti Ìgbò jẹ́ èyí tí ó lọ́wọ̀ tí a kò sì le fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn. Lóde òní, ètò ìṣàkóso ìjọba ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ ti wà lọ́wọ́ àwọn tí ará ìlú fi ìbò gbé síbẹ̀ wọ́n sì ń ṣe ohun gbogbo ní ìlànà òfin, síbẹ̀, àwọn ọba ìlú ṣì ní àgbára lórí àwọn ìjòyè àti ọmọ ìlú ní agbègbè tí wọ́n ti ń ṣe àkóso ṣùgbọ́n òfin ilẹ̀ wa fún ẹnikẹ̀ọ̀kan ní agbára láti gbọn ìyà àti àbùkù nù ní ilé-ẹjọ́.

**Ìpínsísọ̀rí Àwùjọ Ènìyàn**

A lè pín àwọn ènìyàn tí ó wà ní àwùjọ kan sí ìpele mẹ́ta. Ìpele kìn-ín-ní ni àwọn tó wà lókè níbi tí a ti rí àwọn ọba àti ọ̀mọ̀wé. Ìpele kejì ni àwọn tí ó wà ní ààrin, àwọn wọ̀nyí ni kò-là-kò-ṣagbe nígbà tí àwọn mẹ̀kúnnù tàbí tálákà wà ní ìpele kẹta. Ìpele yìí kò dí àjọṣepọ̀ láàrin àwọn ènìyàn lọ́wọ́ ṣùgbọ́n kálukú ni ó mọ àyè tirẹ̀. Àwọn tó wà lókè ló ń ṣe ètò ìlú, ọwọ́ wọn sì ni èlò àmúṣẹ̀dá pọ̀ sí tí wọ́n sì kó àwọn mẹ̀kúnnù sábẹ́ láti máa bá wọn kó ọrọ̀ jọ. Fún ìdí èyí, ẹnu àwọn mẹ̀kúnnù kì í gba ọ̀rọ̀ ní àwùjọ gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú ***Ìgbì Ayé Nyí.***

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Síwájú sí i, a rí i pé ètò nípa ọrọ̀-ajé kò sí ní ọwọ́ àwọn mẹ̀kúnnù ní àsìkò tí Ládélé kọ ìwé rẹ̀ bíkòṣe ní ọwọ́ àwọn ọba. Gbogbo akitiyan àwọn mẹ̀kúnnù láti ní èlò àmúṣẹ̀dá ni ó ti já sí òtúbáńtẹ́ nítorí ìgbàkúgbà ni ọbá lè ránṣẹ́ sí wọn kí wọ́n kó oúnjẹ wá, kí wọ́n fi ọmọge ránṣẹ́ kí wọ́n sì gbé owó wá fún òun. Ní ọ̀nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ọbá lè pàṣẹ kí wọ́n dáná sun ilé ènìyàn gẹ́gẹ́ bí Olú Òtólú ti pàṣẹ kí wọ́n lọ jó ilé baálé Sọ̀ọ́tọ́ nítorí pé ọbá ránṣẹ́ pè é, ó sì ránṣẹ́ padà pé bí sòbìà tí ó dá òun gúnlẹ̀ bá lọ, òun yóò wá. Ẹ̀wẹ̀, ọbá lè pàṣe pé kí àwọn ẹrú òun lọ jẹ oko run. Ayé alárátá báyìí ni àwọn ọba olú-ìlú ilẹ̀ Yorùbá ń jẹ kí àwọn Gẹ̀ẹ́sì tó dé tí kò sì sí ẹni tí yóó yẹ wọ́n lọ́wọ́ rẹ̀ wò.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ju gbogbo rẹ̀ lọ, a rí i pé lítíréṣọ̀ dá lórí àwùjọ àti ìrírí òǹkọ̀wé nípa ọrọ̀-ajé, ètò ìṣèlú, àṣà àti ìbágbépọ̀ ẹ̀dá èyí tí ó máa ń hàn nínú iṣẹ́ aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀, tí ó sì hàn nínú ***Ìgbì Ayé Ńyí*** tí a ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú pépà yìí. Ẹ̀wẹ̀, ó ṣe é ṣe kí á rí àyípadà nípa àwọn ohun tí ó gbé àwùjọ ró ṣùgbọ́n bí àṣà kan ṣe ń lọ ni òmíràn ń dé tí ayé sì ń yí bẹ́ẹ̀ ni bí ayé ṣe ń yí tó yìí, àwọn àṣà mìíràn wà tí kò yí padà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àwọn ènìyàn ní ìlú Òtólú kò dáwọ́dúró láti maa gbé ẹjọ́ lọ sí ààfin níbi tí wọ́n ti gbọ́dọ̀ san owó ìgbẹ́jọ́ dípò kí wọ́n lọ sí àgọ́ ọlọpàá, èyí tí kò ná wọn lówó, wọ́n gbàgbọ́ nínú kí àwọn ṣe é bí wọ́n ti ń ṣe é kí ó lè rí bí ó ti ń rí bẹ́ẹ̀ ni ó sì rí ní ilẹ̀ Yorùba lónìí nítorí àwọn ará ìlú ṣì ń gbé ẹjọ́ lọ sí ààfin ọba tàbí olórí ìlú. Ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá yìí kí àwọn Gẹ̀ẹ́sì tó dé ni Ládélé ya àwòrán rẹ̀ nínú ìwé yìí èyí sì jẹ́ kí á mọ bí nǹkan ṣe rí ní àwùjọ Yorùbá ní ayé atijọ́.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

## Ìwé Ìtọ̀kasí


Adébíyìí, Adékẹ́mi (2012). "Ìfẹsẹ̀lénà àti Ìdàgbàsókè Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ẹ̀ka Ẹ̀kọÈdè Yorùbá. Federal College of Education, Ọ̀ṣíẹ̀lẹ̀, Abẹ́òkúta.

Adélékè, Dúró (2005). "Ìfagagbága àwọn Aláṣẹ àti Mẹ̀kúnnù nínú Fíìmù Ìjà Òmìnira àti Ṣaworoidẹ" nínú Lááńgbàsà. University of Lagos No. 11.

Adéríbigbé, Morónmúbọ̀ (2012). "Tíọ̀rì Lítíréṣọ̀" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ẹ̀ka Ẹ̀kọÈdè Yorùbá. Federal College of Education, Ọ̀ṣíẹ̀lẹ̀, Abẹ́òkúta.

Adéyínká, A. A. (2012). "Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá (Eré-Oníṣe)" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá.Ẹ̀kaẸ̀kọÈdè Yorùbá. Federal College of Education, Ọ̀ṣíẹ̀lẹ̀, Abẹ́òkúta.

Akìwọwọ, Akíntúndé (1983). "Àjọbí and Àjọgbé: Variations on the Theme of Sociation" Inaugural Lecture delivered at the University of Ife Inaugural Lecture Series 46. Ilé-Ifẹ̀: University of Ife Press.

Babalọlá, A. (1967). *Àwọn Oríkì Orílẹ̀.* Glasgow: Wm Collins and Sons Company Limited.

Barber, Karin (1979). ''Style and Ideology in Fagunwa and Òkédìjí'', Seminar Series. Department of African Languages and Literatures. Ilé-ifẹ̀: University of Ifẹ̀ Press.

Eagleton, Terry (1976). *Criticism and Ideology.* London: New York Books.

Fálétí, A. (1969). *Ọmọ Olókùn Ẹṣin.* London: University of London Press.

-------------(1972). *Baṣọ̀run Gáà.* Ìbàdàn: Onibonje Press.

Ládélé, T.A.A. (1971). *Jẹ́ Ng Lo Gba Temi.* Lagos: Macmillian Nigeria Limited.

----------------(1973). *Igba Lode.* Ìbàdàn: Onibọnoje Press.

----------------(1978). *Igbi Aye Nyi.* Ìkẹjà: Longman Nigeria Limited.

Moyra, Haslett (1999). "Introduction: The Politics of Literature" in Julian Wolfreys (ed.) Literary Theories: A Reader and Guide. New York: New York University Press.


UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY

Ògúnṣínà, Bísí (2010). "Ìmọ̀-Ìjìnlẹ̀-Èrò nínú Lítíréṣọ̀: Àgbéyẹ̀wò Bó ti Gbà nínú Yorùbá: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá Nàìjíríà. Vol.6 No.4, June.

Ọ̀gínní, Adé (1982) Àyẹ̀wò Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ilẹ́ṣà: Oyo State College of Education.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọlátúnjí (2003). Òǹkọ̀wé àti Ìwé-kíkọ Alátinúdá (Àtúnṣe Kìn-ín-ní). Ọ̀yọ́: Odumatt Press and Publishers.

Sànyà, Ayọ̀mídé Gbóyèga (2012). "Iṣẹ́ Gbígbòòrò Lomrí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá" nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ẹ̀ka Ẹ̀kọÈdè Yorùbá. Federal College of Education, Òṣíẹ̀lẹ̀, Abẹ́òkúta.

Wellek, R. àti Warren, A. (1949). *Theory of Literature.* Penguin Bookshop.

Williams, Reymond (1978). *Marxism and Literature. London:* Oxford University Press.

UNIVERSITY OF IBADAN LIBRARY